# ELETI ỌFẸ

'A-NJU-WỌN KO ṢE WI LẸJỌ'

VOL XIV NO 891 LAGOS SATURDAY OCTOBER 19 — OCTOBER 25 KỌBỌ MEJI (2D) 1963

### Esu Gbode Logba Ewon Ilesha:

# Awọn Ẹlẹwọn Pa Ara Wọn Ni Owurọ Ana

ILESHA —Gọngọsọ ni ile ọgba awọn ẹlẹwọn nibi ni owurọ ana nigbati awọn ẹlẹwọn ti o wa lọgba na faake kọri nigbati awọn dẹrẹba ọga wọn yan iṣẹ ti nwọn ni lati ṣe lọjọ na fun wọn, ti awọn kan kọ wipe awọn ko ni ṣe iṣẹ, ti nwọn si bẹrẹsi ba ara wọn ja. Ere ni, awada ni, ija na bẹrẹsi tan kalẹ larin awọn ẹgbẹta (600) ẹlẹwọn na.

Ija na pọ tobẹgẹ ti awọn dẹrẹba ọga wọn ko le sun mọ wọn rara lati la wọn, awọn ọlọpa ni nwọn sare pe wa sibẹ, ki awọn ọlọpa na to sare de ọgba ẹwọn, awọn ẹlẹwọn na ti fi igo, ọbẹ ati kunmọ ṣe ara wọn lọṣẹ yanmọyanmọ nwọn si pa ẹnikan ti nwọn npe ni Kọlawọle Afọlabi ninu ara awọn.

Onirohin wa ni wakati mẹta gbako ni nwọn fi ja ija na, awọn miran ti nwọn tun gbọgbẹ ninu awọn ẹlẹwọn na wa ni ile awọn alaisan (Wesly Guild Hospital) nibiti nwọn gbe npọka iku nisisiyi.

Ninu ọdun yi ni nwọn ju Afolabi ẹlẹwọn ti nwọn lu pa yi sẹwọn ọdun mẹrin fun ẹsun wipe o pa Ọlọpa kan ni Ibadan.

## Iya Lasisi "Alufa Oke Arin" Jalaisi N'Idita

EKO — Anu ṣe wa lati tufọ Iya-afin Mọr amọ Ọ ọwunmi Azeez, ọmọ Oloye Shashorẹ l'Eko ti o jalaisi ni oru ana ni namba mẹfa ni Opopo Itọlọ ninu ile awọn ọmọ rẹ. Ẹni adọrun ọdun ni iya ti o jalaisi na, ọmọ mẹjọ ni o si fi saiye lọkunrin ati lobinrin ninu wọn ni Ọgbẹni Yisawu Ayinla Lasisi, ẹniti gbogbo awọn ẹgbẹ rẹ ma npe ni "BABALOKE" ati Isa Akanbi Lasisi ẹniti tọmọde tagba mọ adape oruko rẹ ni "ALUFA OKE-ARIN" oni ṣọbu bia.

( Wo yoku loju ewe kẹjọ)

## Awon Onile Eko Npalemo Ogun Mo Lori Oro Owo Ile Mehaya

EKO....Awọn Yoruba ni bi Awo ti nlu ni Awo njoiyẹn ni ọrọ owo ile mehaya nilu Eko ti awọn oṣiṣẹ ni owo ile oṣoṣu na ga ju pupọ, o si n yọ awọn lorun, ki awọn alamojuto iṣẹ Ijọba Apapọṣe ba awọn ṣe ofin ki nwọn din awọn owo ile na ku.

A gbọ irohin kan ni alẹ ana wipe gbogbo awọn onile ilu Eko, Ebute Mẹtta, Yaba ati Apapa paapa ti npalẹ "OGUN" mọ lati sọ tẹnu wọn, "ogun" na kiṣe ogun ibon ati agba ẹtu ṣugbọn lati sọ fun awọn alamojuto Ijọba bawo ni ọrọ tiri ni.

Akọwe onirohin Eleti-Ọfẹ ni on de ọdọ ọkan ninu awọn baba ẹgbẹ awọn onile Eko na ni ana; mo gbọ wipe nwọn ti ṣe orişirişi eto fun ipade nla kan ti nwọn pe si gbọngan iranti Ọgbẹni J. K. Randle ni Onikan l'Eko ni ọjọ Işẹgun, ọjọ kejilelogun oṣu yi ni ọtunla.

Mo gbọ wipe ipade gbogbogboo awọn baba ati iya onile na kiṣe ọrọ yẹyẹ rara nitoripe awọn na fẹ sọrọ ni iwaju awọn oluwadi Morgan ti nwọn fẹ

ṣe iwadi bi o ba yẹ ki nwọn

fi owo kun owo awọn oṣiṣẹ Ijọba ti nwọn ni

awọn nfẹ ẹkunwo oṣoṣu,

iye owo iṣẹ ti nwọn

nsan fun awọn ko to

awọn na rara, atipa awọn

baba onile fẹ fi owo-ile

oşoşu ti nwọn mbu mọ yi

pa awọn.

PUBLIC NOTICE

There will be a General Meeting of

All Landlords and Landladies

In Lagos And Mainlad

at the late J K Randle Momerial

Hall Onikan, Lagos on Tuesday

October 22nd 1963 at 5 p.m. prompt.

AGENDA: General

CHIEF ALHAJI T.S. CALFOS & OTHERS
Conveners

10 Paley Street,
Epetedo, Lagos.

# Awon Omo Egbe NEPU Pade Agbako Ni Kotu Alikali

KANO—Awọn enia mẹtalelogun ninu awọn ọmọ ẹgbẹ oṣelu kan ti nwọn npe ni NEPU ni Ọya ni adajọ Kotu Alikali Kano sọ sẹwọn ni ọsẹ ti o kọja yi fun ẹsun pe awọn da awọn kan silẹ ninu awọn enia ti Ọlọpa timọle. Ọdun meji ati abẹ ni nwọn ju ẹnikọkan si, nse ni adajọ paṣẹ wipe ki nwọn tọwọ awọn enia mẹta yoku lọwẹ wipe wọn ko gbọdọ ṣe ijangbon rara larin ọdun kan.

Ẹjọ ti awọn Ọlọpa ro mọ awọn enia na ni iwaju adajọ nipe lọjọ kan nwọn ṣigangan wa si teṣan awọn nibiti awọn gbe nṣiṣẹ ni adugbo ti nwọn npe ni Jakara, nwọn fi ibinu da awọn ọdaran ti awọn ti mu pamọ silẹ, nwọn ju ẹdẹgbẹta enia lọ ti nwọn ko ijangbọn na wa si teṣan awọn Ọlọpa.

Awọn Ọlọpa tun ni awọn ọdaran na ten sọrọ abuku si Olotu Ijọba Ipinlẹ Ariwa Ọlọla Ahmadu Bello, nwọn ni ọrọ wọn na le da ijangbọ silẹ nilu.

Awọn ọdaran na li awọn ko gba idajọ adajọ na, awọn fẹ gbe ọrọ awọn lọ si ibiti biriki gbe dunlẹ. Adajọ na ni ki nwọn mọ gba iduro wọn rara. Awọn Ọlọpa lọ janti rẹrẹ lẹjọ ti nwọn ndajọ wọn na.

# Nwon Fe Da Egbe Tuntun Oselu Sile Ni Enugu

ENUGU—Ẹni ọran ndun ṣoro fọrọ lọ ni ti awọn agbẹ, awọn oṣiṣẹ Enugu pẹlu awọn ọlọja ibẹ ti nwọn fi aake kọri wipe dandan awọn ni lati lọwọ si ẹgbẹ oṣelu tuntun ti nwọn fẹ dasilẹ lọdọ awọn. Orukọ ti nwọn fẹ fun ẹgbẹ oṣelu tuntun na ni Ẹgbẹ Abaniwar fun awọn oṣiṣẹ ati awọn agbẹ.

Onirohin wa ni gbogbo adugbo ati arọko ni nwọn ti ha iwe ẹgbẹ tuntun na si ni Enugu, awọn ọmọ ẹgbẹ na si ti kọwe si awọn Ọga Ọlọpa fun iwe ẹṣẹ lati ṣe ipade.

Ọpọlọpọ awọn ọmọ ile igbimọ aṣofin ti ko fara mọ ẹgbẹ kan ni awọn na ti nyọju sita wipe awọn ko lati faramọ ẹgbẹ na ti o ba ti jẹ wipe ire awọn ara ilu ni awọn ti o fẹ da ẹgbẹ na silẹ nwa. Awọn ogunagbongbo ti o fẹ da ẹgbẹ na silẹ lati Eko ti de si Enugu nisisiyi.

# Awon Alufa Meji Nja Lati Di Lemomu

YABA—Adajọ Kotu Ọlọpa ni Yaba fi aṣẹ gba awọn alufa meji ti nwọn nja lati jẹ Lemomu Mọsalaṣi kan ni Sango l'Ebute-Mẹtta nidi wipe on ko gbọdọ gbọ wipe ẹnikẹni ninu wọn ṣe ijọgbọn titi on yio fi gbọ ẹjọ ti ọkan ninu wọn gbe wa si iwaju on.

Lemọmu Abubakar Buhari ti o ti nfi igba kan jẹ lemọmu Mọsalasi kan ti nwọn npe orukọ rẹ ni Jamimiya ni Oke Sango (Old Yaba Road) ni Ebute Mẹtta ni o gbe ẹjọ wa si iwaju adajọ Kotu wipe yiyọ ti nwọn yọ on ni Lemọmu ti nwọn fi ẹlomiran rọpo on ko ba oju mu.

Lemọmu Buhari ni lati ẹjọ ti nwọn ti yọ on, ti nwọn ti we lawani fun Alufa Imoru ni awọn janma awọn ti pin si meji ti agan si fẹ bẹ silẹ ninu Mọṣalaṣi na.

Bi nwọn ba ti ro ẹjọ wọn na si ẹ o ma gbọ nigba miran

## Olopa Mba Awon Akowe Bank Sejo L'Abeokuta

ABEOKUTA—Awọn akọwe ile ifowopamọ (Banki) meji ni awọn ọlọpa Abẹokuta ru wa si iwaju adajọ kotu awọn Ọlọpa n Isabọ ni owurọ ijẹta wipe nwọn ji owo awọn ọga ile iṣẹ wọn gbe ninu ọdun orukọ awọn akọwe na ni Ọlatunji Akano, akọwe agbowo agbowo ati akọwe rẹ Abiodun Akiọde.

Bayi ni iwe ẹsun ti awọn Ọlọpa ka si wọn leti nigbati nwọn ko wọn wa si kotu, nwọn ni ni iwọn nkan bi oṣu mẹta mọ marun ọdun yi awọn Oyinbo onisiga, Nigeria Tobacco Company, ko owo gọbọyi kan wa si ile ifowopamọ (Banki) ti nwọn npe ni Bank of West Africa, nwọn ni gbogbo owo na na - ẹdẹgbarin pọnun (£7,000) ni awọn awọn akọwe mejeji jigbe, ti wọn si lo fun ara wọn

Adajọ ti yio gbọ ẹjọ wọn na ti sun ọjọ ti yio gbọọ siwaju di ọjọ kẹta oṣu ti mbọ.

E ka oro Ayiluka

Nipa awon oselu Alagbara pelu awon Urhobo loju ewe karun.

ELETI-OFE D'ARABA

E polowo Oja yin sinu Iwe Irohin Eleti-Ofe

Losose

O kun fun irohin aladun.

Olofintoto Ni:

# I-y-o

## Boya Ilu Kan Wa Ti Nwon Ki Jee

Ọtọ patapata ni ori ọrọ ti mo fẹ ba ẹnyin ọkawe mi jiroro iwe ninu iwe irohin Eleti-Ọfẹ ti ọsọ yi, ṣugbọn iwe kan ti mo ri gba lati ọwọ Ọgbẹni kan ti o pe ara re ni OJỌGBỌN lati TOTORO ni AGỌ OWU l'ABẸOKUTA ya emi-OLOFINTOTO yin lẹnu pupọ ti emi na fi pinnu lati tẹ iwe Ọjọgbọn na jade wipe ki e ba mi gbe ọrọ na yewo.

Iwe ti mo ri gba jati ọdọ Ọgbẹni Ọjọgbọn na niyi.

"Olofintoto, ẹ jọwọ ẹ ma wipe mo ṣe iyaju si yin nipa iwe ti mo kọ si yin yi. Mo ti nka ọrọ yin ninu iwe irohin Eleti-Ọfẹ ni ọsọsẹ ọjọ ti pẹ, ṣugbọn mo ti nro nkan ti mo titori rẹ kọwe yi si wipe tani o le la mi loye ọrọ na si ti pẹ.

"Laipẹ yi ni ọkan mi wa taji ti mo ro gbogbo rẹ kan yii wipe boya e le ri ẹni ninu awọn ọkawe yin tabi ẹnyin na ni Ọlọrun si fun loye lati le la ibere ọrọ na ye mi.

"Ibere ọrọ mi na niyi Mo fẹ mọ boya a le ri awọn ara ilu kan ninu aiye ti a wa yi ti nwọn ki jẹ IYỌ--ỌBẸ.

"Gẹgẹbi nkan ti gbogbo wa imọ njepa IYỌ, IYỌ jẹ nkan pataki ninu nkan ti a wa laiyọ ti enia ko le saj jẹ lojojuma gẹgẹbi OMI ti jẹ nkan pataki fun awa ẹda aiye.

"Bi enia ko ba jẹ onjẹ ni ojumọ nkankan ko ni fẹ oluwarẹ ṣugbọn ki o ma mu omi fun ọjọ kan gbako on alara a mọ wipe on ti ngba iwe ọjọ iku lọdọ ẹlẹda on.

"Ikeji ọrọ ibere mi na lori IYỌ—ỌBỌ jijẹ na ni wipe ki awọn Oyinbo to de si ilẹ wa bawo ni awọn baba wa ṣe nri iyọ fi si ọbẹ wọn? Ọgbọn wo ni nwọn dan sii.

"Mo gbọ wipe enia ko le ṣeyọ lai jẹ wipe Oluwarẹ lo omi okun (sea water) ti o si se e titi: Ni igbati atijọ ko si ọkọ moto akẹru, ko si ọkọ reluwe, ko si ofurufu ti awọn baba wa ni ilu Oke le lo lati mu wa si eti-okun lati wa pọn omi re lọ si ilu wọn lati sọ diyọ, bawo wa ni nwọn tise ndọgbọn iyọ-ọbẹ wọn na?.

"Nkan pataki ni ọrọ iyọ ati itan atijọ ti o wa nidi re, nitorina mo bẹ yin OLOFINTOTO ati ẹnyin ọkawe wọn ki e sọ itan iyọ ọbẹ na fun wa"

Ọrọ ra niyin o ẹnyin ara wa! Jiji ni mo ji ai emi na ba ila ni atẹlẹwọ mi nko mọ ẹniti o kọ ọ, ṣugbọn boya awọn agbalagba ilẹ wa le sọ itan iyọ-ọbẹ jijẹ na fun wa ni ẹkunrẹrẹ nigba miran. O digba.

# Kiko Ila Ereke (2)

Lati Owo Alufa Atilade

baba", nwọn a dahun wipe, 'Họwu! Ọna oju re n mo wo."

Ijiyan pupọ li o wa loni pe o yẹ ki a ma kọ ila nitoripe aṣa awọn baba wa ni, ko si yẹ ki a ko o silẹ. Nwọn sọ pe olukuluku ẹya enia ati orilẹ ede li o ni aṣa tirẹ. Awọn ti nwọn ba nsọ aṣa ti nwọn nu lati gba aṣa awọn elomiran, ẹru ni nwọn nda ati aiọrọjẹ nwọn a si sọ itan atọwọdọwọ wọn nu.

Awọn enia wọnyi tun sọ pe ila kikọ jẹ ọkan ninu iṣẹ ọna ti awọn Yoruba Iṣẹ ọna ni si jẹ ọna onjẹ ọjọ fun awọn enia ti a npe ni Olola. Bi a ko ba kọ ila mọ, a pa iṣẹ ọna yi run lati fi ohun miran dipo rẹ. Ni akotan, nwọn sọ wipe aikokola yio mu ki a ma sọ enia wa nu yio si mu ki iya ma jẹ awọn ọmọ wa. Ọmọ oniie, ọlọna yio nade awọn ebi iya tabi baba re; ṣugbọn nigbati ko si amin bi ila ẹrẹkẹ lati mọ eso igi ni yio ma jẹ dipo ti iba ma fi ẹdọ ẹran jeun.

Li ẹgbẹ keji ẹwẹ, awọn enia miran sọ wipe, ' han gbogbo ni akoko wa fun. Nkan iran wa ti o dara ni adọta ọdun ti o kọja ṣugbọn ti ko dara to bẹ fun ode oni, gẹgẹbi awọn baba wa iti ma pa a l'owe pe, Aṣọ igba ni a nda fun 'gba. Ko si ẹnikan ti ori re pe ti yio wipe, ile olorule koriko tabi ewe ti awọn baba wa nlo ni adọta ọdun ti o kọja ni on fẹ ni ode oni, nitoripe o jẹ ohun aṣa idalẹ wa.

(wo iyoku ni oju ewe kẹja)

# 'Wayo Olopa' Gbe-wa Osu Mesan

UMUHIA—Ọkunrin kan ti o nla egbogi kiri aroko ilu Ibo ti orukọ rẹ njẹ Rowland Inyang, ẹni ọdun mẹtadinlogbọn ni adajọ kotu awọn ọlọpa, Ọgbẹni Clement Ike sọ sewọn oṣu mesan pẹlu iṣẹ aṣekara fun fifi ara rẹ we ọga ọlọpa.

Bayi ni awọn ọlọpa ti nwọn mu ọdaran na ro ẹjọ mọọ niwaju adajọ, nwọn ni ninu ọsẹ ti o kọja yi ni ọdaran na dide lati ilu rẹ ti o gba ilu okere kan ti nwọn npe ni Amaldiaku Nap lọ.

Nwọn ni nigbati o de ilu na o pe gbogbo awọn kansilọ ilu na ati balẹ ilu na jọ, o ni ọga ọlọpanu ni on, o ni lati Enugu ni nwọn ti ran on wa lati wa ṣe iwadi nipa owo gọbọyi kan ti nwọn ji gbe ninu Banki nla l'Eko.

Ọdaran yi fi iwe fọto ọlọpa kan han wọn ni iwe-aṣẹ on niyẹn, o tun fa iwe kan yọ lapo rẹ o ni namba awọn owo pepa ti awọn ọlọpa na jigbe niyi o ni nitorina ki nwọn lọ ko gbogbo awọn owo pepa wọn jade ki on yẹ wọn wo.

Awọn ọlọpa ni nibi ti o gbe tu ile ọkan ninu awọn ara ileto na ni awọn ọlọpa ti gba ọdaran ọlọpa wa na mu.

# ELETI-OFE

A NJU WỌN KOSE WILẸJỌ )

EDITORIAL OFFICE & WORKS 28, Kosọkọ Street, Lagos. P. O. Box 467

CABLE & TELEGRAM "ELETI-ỌFẸ" LAGOS Phone 23370

VOL XIV. NO 8/1 SATURDAY OCT 19 - OCT 25, 1963


## Oro Olotu:

# Atunka Awon Enia

Ni ilẹ awa Yoruba, awọn agbalagba, awọn baba wa ni owe kan ti nwọn ma npa bayi: "Ogun-a-wi tẹlẹ ki pa enia", iyẹn nigbati nwọn ba fẹ ṣe ikede ọrọ asọtẹlẹ kan fun enia. Nkan ti o jẹ ki awa Oniirohin Eleti–Ọfe yọ iru owe bayi jade fun yin ni nipa ti gbogbo awọn enia ilẹ Nigeria ti nwọn tun fẹ tun ka ninu oṣu ti a fẹ bọ si yi.

Boya ẹnyin ọkawe wa lọkunrin ati lobinrin le gbagbe ọrọ iṣiri ti Olotu wa sọ fun yin ni iwọn nkan bi oṣu mẹwa sẹhin ti awọn ikọ ile igbimọ aṣofin l'Eko fẹ naka si ara wọn lẹju lori abayọri gbogbo awọn enia ti nwọn ti ka na ti eto abayọri na ko ṣe gbe jade.

Eleyi ni ọrọ iṣiti ti Olotu wa fi ṣi yin leti nigbana:

Bi eti ko ba gbọ yinkin inu ko ni bajẹ–Owe awọn baba wa ni ilẹ Yoruba niyi, ṣugbọn ọrọ na ba ọrọ awọn alamojuto Ijọba Apapọṣe wa mu lori ọrọ alaye ti Alhaji Waziri Ibrahim, Minisita alamojuto eto nkan aje to ṣe lori awọn enia ti nwọn ti ka ka-kiri gbogbo ilẹ Nigeria ti nwọn kọ lati gbe iyọri rẹ jade sita fuu gbogbo wa.

Ninu ile Igbimọ awọn aṣofin l'Eko ni ijẹrin, Minisita na sọ fun gbogbo agbaiye wipe gbigbe ti awọn ko gbe iyọri gbogbo tj awọn ka iye awọn enia na si jade ko nṣe ẹbi awọn rara bikoṣe ti awọn aladugbo wa ni Ipinlẹ Ila Orun ni Ila Orun ni ilu Ibo.

Nwọn ni awọn ilu bi Awka, Brass mọ agbegbe Opobo nṣe ni nwọn mbu enia mọ enia ti nwọn ka nitorina nwọn ni lati tun awọn enia ilu ka ni.

Awa oniwe irohin "Eleti-Ọfẹ" lati bi oṣu melo kan ti a ti ri wipe ọrọ awọn enia ti nwọn ka ni di koko ni a nti nte mọ gbogbo ẹnyin enia wa leti, o dabi ẹnipe awọn kan fẹ ṣe aidara nipa rẹ. Awa ko sọ wipe Ipinlẹ kan ni o jẹbi ọrọ na, ṣugbọn on a fẹ fi setigbọ yin ni wipe ki ẹ maṣe ọrọ na ni "ẹniti o ba ka mi ka igba iyà rẹ" ki ẹ jẹki nwọn ka ọ tọmọ-tọmọ ati tọkọ-tọkọ.

Ọrọ re o, ẹnyin ara wa ọmọ Yoruba, ẹ ṣe agbara ki ẹ ran awọn enia ti nwọn ba ran wa si ile yin ati adugbo yin lọwọ, ki ẹ jẹ ki nwọn le ri yin ka daradara. Ọrọ ti nwọn ba bi yin lere ki e da wọn lohun ni idahun ọmọluwabi, ki ẹ maṣe da apara alaifaṣa fun wọn

Olukuluku ni o nwa ire fun iran rẹ, ẹ jọwọ, a bẹ yin ẹ maṣe jẹ ki ire ẹhin ọla ko fo awọn ọmọ wa da. Ẹ jẹki nwọn ri yin ka ninu oṣu ti mbọ.

# Iwe Si Olotu

## Ija Ilara Ni Na?

Nigbati mo ri ka ninu iwe irohin wipe awọn Kansilọ ti awọn ara Eko ran lọ si ile igbimọ Ijọba ibilẹ Eko, oju ti mi pupọ nitoripe iru iwa bayi ta abuku fun awọn Kansilọ na.

Bi oju ko ba ti wọn, o yẹ ki oju ti awọn ti nwọn yan wọn ni aṣoju si ile igbimọ na nitoripe nwọn ko yan wọn sibẹ lati ma lọ ja gidigbo rara.

Olotu ẹ jọwọ, ẹ ba wa sọ fun awọn alatako, awọn ọmọ ẹgbọ Alakukọ (N.C.N.C.) ki awọn na fun awọn ti ara ilu Eko ran lọ sibẹ igbimọ laye la tiṣe igba tj wọn ki a le ri nkan sọ bi nwọn ba ti lo akoko ti nwọn na si.

O dabi ẹmi wipe awọn Kansilọ ọmọ ẹgbẹ Alakukọ (NCNC) yi nfẹ ṣe aṣeju, bẹ aṣeju si ni baba aṣetẹ. Bi o ba jẹ awọn ọmọ ẹgbẹ Ọlọpẹ (AG) paapa ni o kọ lati kuro lori aga fun awọn ọmọ ẹgbẹ oṣelu ti o wọle o ni iru orukọ ti a o ti ma pe wọn kakiri arin ilu.

Iwa anikanjọpọn bayi ko dara. Bi a ba ti fẹ ki enia ṣe si wa ni o yẹ ki awa na ṣe si wọn.

Ọrọ mi ko ju bayi lọ. Olotu iwaju ni ọpa ẹbiti yin yio ma resi.

Emi ni,
Oke Bode, Ibadan. S Ọyalọla

## Alailojuti Ni Won Nitoto

Ọrọ Olotu iwe Eleti-Ọfẹ ti o sọ nipa awọn Kansilọ wa, awọn ti nwọn ko mọ bi nwọn tiṣe ntiju, ti nwọn lọ sile ana wọn, ti nwọn lọ ku sibẹ, ni mo fẹ kan sara si.

Ki a ma purọ tan ari wa, mo gba fun ọrọ Olotu na, o kan oju abẹ niko. Inu wa yio dun bi a ba nri iru awọn oniwe irohin bayi ti nwọn yio ma ba wa sọ otitọ ọrọ fun awọn ikọ ti a nran lọ si ile igbimọ aṣofin ati ti ijọba ibilẹ.

Bi o ba jẹ bayi ni awọn kanselọ Oyinbo ti nja nilu wọn lori a gbeṣe fun ni, a ko gbeṣe fun ni, aiye a ti bajẹ tipẹ tipe.

Olotu, mo gba fun yin, ẹ jọwọ ẹ tun ma ba wa sọrọ fun wọn ki nwọn le ronu pa iwa buruku wọn da.

Emi ni,
Ilupeju Mushin. J O Atunraṣe

## Ajala Tani Na o ...?

Olotu, ẹ jọwọ mo fi irẹlẹ bẹ yin, ki ẹ ba mi fi iwe mi yi fun OLOFINTOTO Eleti-Ọfẹ nitoripe nigbati mo ka iwe kan ti Ọgbẹni Agbakosi Ilubajẹ kọ sii lori bi ọrọ ilu ti nlọ si ni ilu wa yi ati esi tj o fun Ọgbẹni na ẹrin pa mi pupọ.

Otitọ ọrọ ni esi ti Olofintoto na sọ ti o wipe ọrọ wa ti di ọrọ Ajala Tani Na ọ? Mo sebi awa ara ilu ni a mba awọn oṣelu wa ja, ti a pọn wọn lehin, ti nwọn fi ogo wa jẹ.

Ti o ba nwa awọn aturọta bi elubọ ki o lọ sọdọ awọn oselu wa. Mo tilẹ ro wipe ti a ba ti dibo fun wọn, ti nwọn ba ti wọle igbimọ, ti nwọn ba ti bura tan, o ni ile ẹkọ-irọ-pipa ti nwọn ma nlọ kọ wọn nibẹ.

Akara fẹrẹ tu sepo na, ki a rọju, o ku diẹ; boya nwọn a le mọ wipe otitọ lẹju.

Emi ni,
Oro leti Ilọrin John Ade

# Nihin Lohun Ati Nibi Gbogbo

## Lati Owo Ayiluka

Ẹnyin ọkawe emi Ayiluka ti o wa nile ati ẹnyin ti ẹ wa ni idalẹ mo ki yin pupọ wipe ẹ ku atijọ. Ṣe alafia ni awọn ara ile wa? Ṣe odẹdẹ ko gbona? Emi na ti mọ wipe ọpọlọpọ yin ni yio ti ma wo inu iwe Eleti-Ọfẹ ni ẹsọsẹ lati gbọ tẹnu mi. Ẹ ṣe pupọ!

### Awon Alagbara

Ọrọ awọn alagbara ti mo fẹ mu ẹnu kan yi jẹki nniran ọrọ inu Bibeli ti o sọ ita pupọ nigba awọn alagbara inu aiye atijọ ati bi ọpọlọpọ wọn tiṣe ṣubu. Ọba Ti NEBUKARINESARI ni a fẹ fẹnu kan ni tabi ti SAMSON alagbara?

Idibo ti nwọn di ni agbedemeji Ipinlẹ Iwọ Orun tuntun (Mid-West) ni ọsẹ ti o kọja yi ya ọpọlọpọ enia lẹnu bi ayọri si idibo na ti jasi, ṣugbọn ayọri si idibo na ko ya mi lẹnu rara nitoripe awọn alagbara oṣelu kan ni nwọn ṣe faari ti awọn ọmọ ẹgbẹ Olomi (NPC) fi kele gbe wọn ni Warri.

### Se Faari

Awọn Urobo ko jẹbẹ rara. Mo gbọ wipe "Balogun" oṣelu kan wa ni ilu Warri ti orukọ rẹ njẹ Alhaji Warri ti o mọ nkan ti o nṣe nilu Warri ati ni agbegbe arọko ibẹ. Awọn ọmọ ẹgbẹ Alakukọ fi igbakan ko iyan rẹ kere, o si fi agbara han wọn.

Awọn mẹta ninu awọn ọmọ ẹgbẹ Alakukọ (NCNC) ni anu wọn ṣe mi pupọ ninu ọrọ idibo ti o bẹ silẹ ni ilu awọn Urhobo na Emi Ayiluka a fi orukọ bo wọn laṣiri ṣugbọn ọrọ awọ.ı DO! OBO ADORI, ADORI NAGAGA yi jẹki nniran orin kan ti nwọn kọ l'Eko ni ıwọn nkan bi ọdun mọkanlelogun nigbati awọn ara ilu Warri pe awọn ara Sapẹlẹ lẹjọ lori ọrọ ile; Orin na lọ bayi.

"Isobo Winni o,
"Istekiri Lusi o
Isobo Winni,

Lati ọjọ na ni awọn ara Eko mọ̀ Ibadan ti npe wọn ni ISOBO WINNI.

### Kele Gbe E

Nitorina ọrọ awọn URHOBO WINNI yi kiṣe ọjọ oni, nwọn ti nwinni (ṣẹgun) ọta wọn



Oloye ỌLAREWAJU

bọ ọjọ ti pẹ. Ọmọ Urhobo ni Oloye S.J. Odjie, ọmọ ẹgbẹ Alakukọ (NC C) ti o ni ki awọn ara ilu on dibo fun on. Mo gbọ wipe awọn Iyawo rẹ ati ọmọ rẹ nikan ni nwọn ju iwe idibo mẹrin pere sinu apoti tirẹ, eleyi ara! Boya eleyi le kọ awọn alagbara wa awọn ti wọn lero wipe ko si nkan ti awọn ko le fi owo ra lọgbọn. Iyẹn bẹ.

## Oba Kano O Digba!

O dun mi pupọ lati gbọ iku Ọba Kano Alhaji Muhammadu Inua Abbas ti o ṣẹṣẹ jọba ilu Kano ninu ọdun yi nigbati ẹgbọn rẹ binu fi ori itẹ silẹ: Ọjọ meje ni o din ni igba ọjọ ti ọba na fi lo itẹ rẹ na

Emi Ayiluka ko mọ ologbe ọba na dara ṣugbọn ẹgbọn rẹ ni mo mọ ti on alara paapa si mọ mi; Ọba ana na tilẹ mu mi lọ silu kan ti nwọn npe ni Bichi ni arọko Kano, o si ṣe mi ni alejo pẹrẹwu nigbati o wa ni ARẸMỌ ỌBA: Ju gbogbo rẹ lọ Anabi ki o gbee si afẹfẹ rere ki o si pẹlu ibatan rẹ, Alhaji Ado Bayero, Ọba Kano tuntun ti yio ṣẹṣẹ jẹ ki ori Oriṣa Kano gbe gbogbo wọn.

## Ile Ife Ku Ajalu

Ajalu nla ni eyi, ọmọ Ọba Ile Ifẹ ti o jalaisi ni ijẹrin ni Ikeja. O ya mi lẹnu lati gbọ iku adajọ Kotu awọn ọlọpa ọmọba Adedapọ Aderẹmi ti o jalaisi-ẹni ọdun mọkandinlogoji ni arakunrin na, aisan kekere kan ni a gbọ wipe o ṣe a ko mọ wipe ỌRỌ ỌLỌJỌ ni.

# Eleti—Ofe D'araba




# Fila Ori Kan Tu Asiri Re

KADUNA—Gbogbo awọn ero ti nwọn wa si Kotu Boda-o-wa kan ni Kaduna lati wa gbọrọ ni nwọn bu sẹrin lojiji niwaju adajọ ti awọn ọlọpa sọ fun wipe fila ori ọdaran kan ti orukọ rẹ njẹ Ayọdele Ọpadokun ọmọ ara Ọffa ti o sesi gbagbe silẹ nibiti o gbe ti lọ ko ile ni awọn tọpasẹ rẹ, ti awọn si mu ni ilu rẹ ti. Ọffa nibiti o gbe salọ.

Ẹwọn ọdun meji pẹlu iṣẹ asekara ni adajọ kotu ti nwọn ro ẹjọ esun ole ti nwọn fi Ayodele na sun niwaju rẹ. fi si nigbati o gbọ ọna ti o gba jale nile ọrẹ rẹ.

Awọn ọlọpa ni ẹdaran yi lọ sile ọrẹ rẹ ni opopo Kabba Ọgbẹni Owolabi kan nigbati iyẹn lọ si ibi iṣẹ rẹ, nibiti ọ gbe ti nji ẹru ọrẹ rẹ ko, ọdaran yi igbagbe fila ka ti gbogbo awọn ọrẹ rẹ mọ mọọ sinu iyara Ọgbẹni ti o lọ ji ẹru rẹ ko. Gbogbo ẹru ti ọdaran na ti ji ko le ni poun merindinladọta.

Gbara ti ọdaran yi ti ko awọn ẹru yi tau, ilu rẹ ni Ọffa ni o gba lọ ibẹ ni ọwọ awọn ọlọpa ti tẹẹ.

# Kiko Ila

O bẹrẹ loju ewe kẹta

Awọn enia wọnyi sọ wipe aṣa ki a aṣa ti o ba akoko igba owo ẹru mu; ṣugbọn loni ko si owo ẹru mọ, eṣe ti a o tun fẹ ati ma fi ila ẹrẹkẹ ranti owo ti o mu ipọnju, ẹkun ati ibanujẹ ti a ko le fi ẹnu sọ wa fun awọn obi wa igba lailai?

Awọn ti nwọn sọ wipe ki a pa aṣa kikọ ila ẹrẹkẹ run tun ṣe alaye pe ni atijọ, awọn ẹya kan ki iba ẹya miran lo bikoṣe lati ba ara wọn jagun. Olukaluku duro ninu ala ilu tirẹ; ṣugbọn ko ri bẹ ni ode oni. Ọfiọ ilẹ, Ọkọ oju omi, Motor, Ọkọ ofurufu ati Redio ti sọ gbogbo aiye di arugbo kan ṣoṣo.

Owo sisẹ ati ibalopọ wa larin awọn orilẹ ede ti o le ti ilẹkun mọ awọn enia rẹ pe ki nwọn ma jade lọ si ilẹ miran tabi ki awọn ara ilẹ miran maṣe wọ ile fun akoko pipẹ pelu irọrun.

Awọn ọmọ ti nwọn nkọ ila, ti nwọn si ti jade lọ si ilẹ miran pada bọ lati sọ fun wa pe awọn kan ọpọlọpọ abuku ati itiju nitori ila ti nwọn kọ.

Gbogbo awọn orilẹ ede aiye ni nwọn nwo awọn bi ajeji enia ti ko yẹ ki a sunmo nitorina ila ẹrẹkẹ ti o ti jẹ ohun anfani fun enia nia ni aiye awọn baba wa di ohun ori buruku ati itiju ni aiye ti awa ọmọ wọn nitori eyi, o yẹ gi a kọ aṣa na silẹ:

Ni ipari, nwọn ni ki a ko ọrọ na dan pe ila kikọ kou jẹki a sọ ẹbi ẹni nu. Nwọn ni awọn ẹya miran, gẹgẹbi awọn ara Ile-Ifẹ wa larin awọn Yoruba tij nwọn ko kọ ila ẹrẹkẹ ti nwọn ko si sọ ẹbi wọn nu ; ki a ma tilẹ toka si ogunlọgọ awọn orilẹ ede ati ẹya ni dudu, funfun, ipupa ati ofefe ti nwọn ko nkọ ila ẹrẹkẹ ti nwọn ko si sọ ẹbi tabi ẹya wọn nu

Bi a ba ro ọran yi ni ẹgbẹ kini ati ẹgbẹ keji, ti a si fi anfani ti o wa ninu ila kikọ we adanu, ẹgan, ati abuku ti o wa ninu rẹ, a o gba pe o yẹ ki a mu aṣa kikọ ila ẹrẹkẹ kuro atapata, nitoripe asọ igba ni a nda fun 'gba.

# Eleti—Ofe D'araba

# Alo o !

1) A ko odo rin, a ko wọ rin igẹgẹ ẹhin yọ sita
2) A ran ọmọde lọ rọ akara, akara ṣiwaju rẹ de
3) Igi buruku ti igba nsunkun.
4) Alẹ nlẹ onikoko ko koke jọ.
5) Ọpẹ ku mariwo njọga.
6) Aboyun pupa tu itọ funfun.
7) A gbe oku lọ sọja oko rẹ nlẹ.
8) Orukutinditindi okurutinditidi oruku bi igba ọmọ gbogbo rẹ je ajẹ.
9) Ko lọwọ ko lẹsẹ o ngbọmọ jo
10) Mo duro o duro mo bẹrẹ mo titi ko lọ.

## ITUMO

(10) Ojiji
(9) Ibusun
(8) Ata
(7) Ọgẹdẹ ẹun
(6) Ọsan agbalu-
(5) Iru ẹṣin
(4) Ori
(3) Ibọn
(2) Ẹyin ọpẹ
(1) Efin


# E ma ka

## Iwe Irohin Eleti-Ofe

To kun fun irohin aladun

Losose

**Sequel To Boycott:**

# New Election For Kenya's Northeast Region

NAIROBI—New elec ions are to be held in Kenya's North-Eastern Region, where Somali secessionists staged a total boycott in the general elections earlie this year.

During the weekend the Kenya Government in Nairobi released the text of a message from Mr. Duncan Sandys, Secretary of State of Commonwealth Relations and the Colonies to Sir Eric Griffits-Jones, Acting Govenor of Kenya.

The elections will be for National Assembly seats and for a Regional Assembly. At present the North-Eastern Region is governed directly by the Governor with special powers made available to him since the boycott.

The elections will be held either before or after indepence, and Mr. Sandys states: "These arrangements will give adequate opportunity to the inhabitants of the North-Eastern Region to enjoy in full measure these benefits of the new constitution which are expressly designed to give all the people of Kenya a large measure of self government in the conduct of local affairs."

Mr. Sandys adds that he hope soon to announce the conclusions reached at Kenya's Independenc Conference in London, but is already able to give an assurance that the present human rights provisions will be continued in the Independence Constitution and will be among those be given the strongest entrenchment.

He adds: "The Government of Kenya have also reaffirmed their intention that the regional structure of the constitution shall be maintained and that this also will be strongly entrenched."

## Nigeria's Aviation Minister Meets Duke Of Devonshire

LONDON—The Hon. M. Amechi, Nigeria's Minister of State for Aviation, who arrived in London recently is today called on the Duke of Devonshire, British Minisiter of State for Commonwealth Relations during the week.

After talks with the Duke he had further discussions with Sir Andrew Cohen, Director General of the Department for Techinical Co-operation.

He was guest of honour at luncheon given by Mr. Neil Marten, Parliamentary Secretary to Britain's Ministry of Aviation.

On Thursday he flew by helicopter from Battersea Heliport, in the heart of London, to Gatwick Airport where he spent the morning tourning the Airport and the installations of British United Airways.

He returned to Nigeria by air yesterday.

**Letter to the Editor —:**

## Unlawful Seizure Of Private Property

The Lagos City Council have recently intoduced a System by which a person can be deprived of his property by some Overzealous workers of the Council under the cover of a byelaw.

Some Private Car owners have of late experienced disgrace and inconvinence by having their cars towed away by unathorised Workers of the Lagos City Council, the only excuse was that such cars were not properly parked.

I know there is a byelaw which empowers the Council to abate nuisance in the street or permit notices to be served on person whose property may be considered to constitute a danger, nuisance or obstruction to the Public or other users of the road, but that byelaw does not allow the Council, or its Workers to take away people's property without Authority.

There are in very many Streets in Lagos old, unserviceable, unmovable Vehicles where Mosquitoes and human beings breed. This nuisance which some peple use as sheds, restourants and stalls do not gain the attention of the City Council Workers. Private cars owned by responsible Citizen have become the pray of the Lagos City Council workers. Some Cars were removed without regard for the Safety of properties kept in the cars. Some were towed regardless to mechanical faults. These sins are committed under the guise of a byelaw and not the traffic Ordinance to which the Police is responsible.

The Town Engineer should let the Public know the Section of the byelaw and people will know exactly what to do.

A Victim of this byelaw pays a penalty of £5 5s or £15 acccording to the seize of the car. He has no defence, his property is unlawfully seized. I say this without any fear that revenues that have been Collected under the guise of the byelaw is to say the least arbitrary.

Yours etc.,

TAJU THOMPSON.

**Read**

**And**

**Advertise**

**In**

**Eleti–Ofe**

# British "African Chief" Dies

LONDON—A former Managing Director of the Cadbury Cocoa Company who was made an honorary African chief and given the title "Akyempemhene" "given of thousands" died at the weekend at his home in Birmingham. He was Mr. William Hood, aged eighty He was bonr. in Edinburgh and began work at the age of thirtyen in a Glasgow shipyard where his job was to open and close the main gates.

He joined Cadbury in 1919 and became its Managing Director in 1943, a position he held for ten years. He became particular y well known in the cocoa trade for his researsch into the control of wollen shoot disease, al constant problem for cocoa growers.

In 1947 he was made an African chief "in appreciation of his co-peration and friendliness to the Gold Coast." He was presented with a symbolic stool and sandals by Nana Ofori Atta, Second Paramount Chief of the Akyem Abuakwa.

Mr. Hood represented the industry in many negotiations with Government bodies and took a leading part in industrial talks involving West African Countries.

## Iya Lasisi Alufa Oke-Arin Jalajsi

(O bẹrẹ loju ewe Kinni)

Ibi isinku iya na dun pupọ. gbogbo awọn Imale Olowogbowo, Isalẹ Eko, Ereko, Idumọta, Suru Lere ati Ebute Metta mọ Yaba ni nwọn pesẹ sibẹ pẹlu awọn Oloye ilu Eko nitoripe ọmọ oye ni iya paapa ti o jalaisi.

Lẹhinti awọn Lemọmu ati awọn Alufa jankanjankan ti kirun si oku na lara tan ni awọn oguologo enia wa tẹ le oku na lehin lọ si itẹ oku awọn Imale ni Oke Suna nibiti nwọn gbe ti

Gbara ti awọn ọmọ oloku ati awọn ọmọ ọmọ oloku ti pada de ile ni nwọn ti bẹrẹsi ha owo fun gbogbo awọn ti nwọn wa ki wọn.

Orukọ awọn diẹ ti a le tun da niyi ninu awọn ọmọ oloku ni ati awọn ọmọ ọmọ wọn, awọn bi Iyaafin Saratu Otukoko, Olaide, Ariyọ, Nimọta Azeez, Satamọtu Alabi, Bintu Alabi, Ayọka Azeez, pẹlu awọn ọmọ ọmọ bi Tajuden Azeez, M Adio Azeez, S A Azeez, M A Azeez, Latifat, Wosilat, Muyinatu, Mufu, Marufu, Y K., Faosat, Ramọta, Sidikatu, Falilatu, Latifu ati Yẹkinni Azeez:

A ki awọn ọmọloku ati awọn ẹbi Oloye Shashọrẹ, ẹ ku asẹhinde.


Make it a Successful SEASON

with Mercedes-Benz TRUCKS

MERCEDES-BENZ



LEVENTIS MOTORS LTD.
LAGOS (E.B.), IBADAN, KANO, KADUNA, JOS, PORT-HARCOURT, ABA.

*Sub-Distributors:—*

ARMELS TRANSPORT LTD.
BENIN-CITY . ONITSHA . ABA.


Printed and Published by The Union Printing and Publishing Company, 28, Kosoko Street, Phone 2337 Lagos; Editor (Olotu) Ọla Ọnatade, 15, Kosoko Street, Box 467, Lagos.